IVADO

Initiative IA + Société
AI + Society

# AI nínú àpótí ìdìbò

## Ìgbésẹ̀ mẹ́rin láti dá ààbò bo ètò ìdìbò àti mú ìṣèjọba àwaarawa dúró ire[1]

Catherine Régis, Florian Martin-Bariteau, Jake Okechukwu Effoduh, Juan David Gutiérrez, Gina Neff, Carlos Affonso Souza and Célia Zolynski

## Kí ló dé tí AI àti ọ̀rọ̀ ìdìbò ṣe jẹ́ àkọ́lé pàtàkì

Technology Ìmọ̀ ẹ̀rọ máa ń ní ipa lórí ètò ìdìbò láti ọjọ́ pípẹ́, yálà ní dáadáa tàbí ní ìdàkejì, èyí tó máa ń ṣe àyípadà sí èsì àti ìwòye àwọn èèyàn lórí ìtàkusọ̀rọ̀ tó bá ń wáyé lórí rẹ̀. Bí àpẹẹrẹ, ìtàkùn ayélujára fún àwọn ará ìlú ní àǹfàní láti kóra wọn ní ìjánu ju àtẹ̀yìnwá lọ, tó sì ń fún wọn ní agbára láti pè fún àwọn ohun tí wọ́n ń fẹ́ àmọ́ bẹ́ẹ̀ náà ló jẹ́ orísun láti fi gbé àwọn ìròyìn òfégè jáde.

Ìmọ̀ ẹ̀rọ Artificial Intelligence (AI) ṣàgbégdìde ìdúnkokò ọ̀tun, tó fi mọ́ mímú àlékún bá àwọn ìròyìn òfégè, pípọnkún ewu orí ayélujára, àgbédìde àwọn alágàbàngebè àti ìtànkálẹ̀ àwọn ayédèrú àkàǹtì.

Bákan náà ni AI fún àwọn olóṣèlú ní agbára láti ní àjọsepọ̀ pẹ̀lú àwọn olùdìbò, àǹfàní láti yí ọkàn àwọn ará ìlú padà, àti láti ṣe atọ́nà báwọn ìròyìn ṣe ń jáde. Nípa ṣíṣe àmúlò àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tó gbilẹ̀ tẹ́lẹ̀ nípa ètò ìdìbò, AI ní àǹfàní láti ṣe àtúntò ètò ìṣèjọba àwaarawa lọ́jọ́ iwájú àti níní ipa lórí àbájáde àwọn èsì ìbò. Tí kò bá sì ọ̀nà láti tètè jí gìrì, ó ṣeéṣe kí AI mú àwọn nǹkan tó le mú ìbẹ̀rù dání.

## Awọn gbigba bọtini

- Àwọn àpẹẹrẹ láti Brazil, Romania, Gabon àti United States àtàwọn orílẹ̀ èdè mîì ti ṣàfihàn báwọn olóṣèlú ṣe lè lo AI láti dójú ètò ìdìbò àti ìjọba àwaarawa bolẹ̀.
- Ọ̀pọ̀ àwọn orílẹ̀ èdè ni kìí gbáradì fáwọn ìpèníjà tó lè tara AI jáde: ọ̀pọ̀ àwọn orílẹ̀ èdè ni kò ní òfin tó de AI lílò lásìkò ètò ìdìbò, àwọn ẹgbẹ́ ṣẹ̀ṣẹ̀ wáyé láti Brazil, Romania, Gabon, òṣèlú kò ì tîì fẹnukò lórí ìlànà ètò ìdìbò tó yẹ lásìkò ayé AI yìí àti ọ̀pọ̀ ni kò ní ìkápá láti kojú àwọn ìpèníjà tì AI ní lórí ètò ìṣèjọba àwaarawa.
- Àwọn ìgbésẹ̀ mẹ́rin ni a rò pé ó yẹ láti gbé: ìjọba nílò láti ṣàtúnṣe àwọn òfin ètò ìdìbò (fún àpẹẹrẹ láti fòfin de lílo AI láti ṣe àwọn nǹkan tó lè ṣi ará ìlú lọ́kàn); àwọn ẹgbẹ́ òṣèlú gbọdọ̀ ní ìlànà ìhùwàsí lórí lílo AI fọ́rọ̀ òṣèlú; àwọn aláṣẹ ètò ìdìbò ní láti gbé ikọ̀ kan dìde.

# Báwo ni AI ṣe jẹ́ ìdúnkokò sí ètò ìdìbò àti ìṣèjọba àwaarawa

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ọ̀nà táwọn olóṣèlú ń gbà lo AI - lábẹ́lẹ́ àti nílẹ̀ òkèrè – ló lè ṣàkóbá fún àbájáde èsì ìdìbò àti ètò ìsèjọba àwaarawa. Bí àpẹẹrẹ, ètò ìdìbò wáyé ní Brazil nínú oṣù Kẹwàá, ọdún 2024. Ìwádìí kan tí Digital Forensic Researh Lab ṣe ṣàfihàn pé láàárín oṣù mẹ́fà sí ètò ìdìbò náà ni àwọn olóṣèlú tàbí àwọn alátìlẹyìn wọn ṣàmúlò AI ní ìgbà márùndínlọ́gọ́rin (75) láti fi pèsè àwọn àwòrán, fídíò, àti láti fi ká ohun lójúnà àti mú ìgbéga bá olùdíje wọn tàbí tàbùkù àwọn alátakò. Ní pàtàkì, àwọn olùdíje tó jẹ́ obìnrin márùn-ún ni wọ́n gbé ayédèrú fídíò ìbálòpọ̀ wọn síta,[2] ìgbésẹ̀ yìí jẹ́ ipa láti mú ìrẹ̀wẹ̀sì ọkàn bá àwọn obìnrin láti yé dupò òṣèlú àti láti dé àwọn ipò tó ga lágbo òṣèlú.[3]

Àjọ ọ̀tẹlẹ̀múyẹ́ ilẹ̀ òkèrè fún Romania jábọ̀ nínú oṣù Kejìlá ọdún 2024 pé Russia gbìyàjú láti ní ipa lórí ètò ìdìbò ààrẹ orílẹ̀ èdè náà. Àkọ́kọ́, Russia ló àwọn olóṣèlú àtàwọn ọ̀rọ̀ tó ń ṣègbè fún Russia àti lílo AI láti fi gbé àwọn ètò lọ́kan-ò-jọ̀kan jáde tí wọ́n sì pín wọn kiri lórí ayélujára àtàwọn ìkànnì ayélujára tí wọ́n fi AI ṣe. ìkejì, pẹ̀lú ìrànlọ́wọ́ AI (èyí tó le ṣe ìrànwọ́ láti pèsè ìmọ̀ ẹ̀rọ “malware” tó máa ń lọ́wọ́ lílu òfin ìwà ọ̀daràn orí ayélujára), Russia ṣe ìkọlù 85,000 sí àjọ tó ń rí sí ètò ìdìbò Roman lójúnà àti lè rí ààyè wọ ibi tí àwọn àkọ́ọ́lẹ̀ àjọ náà wà lórí ayélujára. Ìgbésẹ̀ Russia yìí mú kí ilé ẹjọ́ Romania fagilé ètò ìdìbò ààrẹ tí wọ́n kọ́kọ́ ṣe.[4]

Lásìkò ìpolongo ìbò ní Gabon lọ́dún 2023, ìfanfà kan wáyé báwọn olùdìbò ṣe ń gbáradì fún ètò ìdìbò ààrẹ, ilé aṣòfin àti ìjọba ìbílẹ̀. Lásìkò tí ìpolongo náà ń lọ sópin, fọ́nrán kan jáde lórí ayélujára, èyí tí wọ́n fẹ̀sùn kàn pé àwọn alátakò méjì kan gbòógì ló ń sọ̀rọ̀ níbẹ̀, níbi tí wọ́n ti ń jíròrò lórí bí wọ́n ṣe máa fọwọ́sowọ́pọ̀ àti bèèrè fún ìrànlọ́wọ́ láti ilẹ̀ òkèrè. Ààrẹ tó wà lórí ipò fẹ̀sùn kan alátakò pé wọ́n mọ̀ọ́mọ̀ fẹ́ dá làásìgbò sílẹ̀ àmọ́ àgbáríjọpọ̀ àwọn alátakò bu ẹnu àtẹ́ lu fọ́nrán náà, tí wọ́n sì júwe rẹ̀ bíi lílo AI lọ́nà tí kò bójúmu. Ìṣẹ̀lẹ̀ ti Gabon yìí ṣàfihàn bí àmúlò AI ṣe le mú ìtàkurọ̀sọ ìta gbangba lọ́júpọ̀, léyìí tó máa jẹ́ kó ṣòro fáwọn olùdìbò láti lè ya òótọ́ sọ́tọ̀ kúrò nínú irọ́.[5]

Ní ìkádìí, àwọn onímọ̀ ṣàyẹ̀wò ìlànà AI lásìkò ìpolongo ètò ìdìbò ààrẹ ilẹ̀ Amẹ́ríkà tọdún 2024 lórí ọ̀nà tí wọ́n ń gbà gbé ìròyìn tó péye jáde nipa ètò ìdìbò náà. Àbọ̀ àwọn ìwádìí náà rí àwọn àìṣedédé lórí pawọn ìròyìn kan ní èdè ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀, àti láàárín ọ̀rọ̀ ìfarajìn táwọn iléeṣẹ́ AI ṣe àkọ́ọ́lẹ̀ rẹ̀ láti pèsè àwọn ìròyìn tó péye lórí ètò ìdìbò àti bí àwọn ìlànà wọn ṣe pójú owó sí.[6]

Àwọn àpẹẹrẹ yìí ṣàfihàn báwọn orílẹ̀ èdè àtàwọn ìjọba kìí gbáradì de àwọn ìpèníjà tí AI máa ń mú dání. Àwọn alàkalẹ̀ wa wòye ọ̀nà láti dènà tàbí mú àdínkù bá ipa burúkú táwọn ìmọ̀ ẹ̀rọ tó ń gbòòrò le ní lọ́rí àwọn ètò ìdìbò.

***Àwọn ètò ìdìbò abẹ́lé ni ipa AI le ṣàkóbá fún jùlọ, bí ó ṣe jẹ́ pé ètò ìṣèjọba àwaarawa kò ní àwọn ohun ìnílò láti kojú àwọn ìpèníjà tò bá ṣẹ́yọ bó ṣe yẹ.***

## Ìpèníjà àkọ́kọ́
## Ọ̀pọ̀ àwọn ìjọba ni kò ì tíì máa ṣàmúlò òfin tó de lílo AI lásìkò ètò ìdìbò

Àìsí òfin kan pàtó tó fidí múlẹ̀ nípa ìṣàmúlò AI lásìkò ètò ìdìbò fàyè sílẹ̀ fún àìsí ìlànà kan tó tọ́nà lórí ìṣàmúlò òfin, èyí tó jẹ́ kó ṣòro fáwọn aláṣẹ láti gbé ìgbésẹ̀ tó yẹ tako àìṣàmúlò AI lọ́nà tí kò tọ́.

Ọ̀pọ̀ àwọn òfin ètò ìdìbò káàkiri àgbáyé ni wọ́n máa ń ṣàmúlò láti ọ̀pọ̀ ọdún kí AI tó gbajúmọ̀, kí wọ́n sì tó máa lò ó káàkiri. Fún ìdí èyí, ó nira láti sọ ní pàtó pé báyìí ló yé láti kojú àwọn ìpèníjà tí AI le fà nítorí bí ó ṣe gbòòrò. Bí àpẹẹrẹ, ọ̀pọ̀ àwọn ìgbésẹ̀ ìṣòfin ni kò ní ìtúmọ̀ fún “synthetic media” tàbí àwọn “ètò tí wọ́n fi AI ṣe”, tí wọ́n sì kùnà láti la ibi tí ọwọ́jà lílo rẹ̀ gbọdọ̀ dé nígba tí wọ́n bá ń lò ó f;un ètò ìdìbò.

Àwọn ilé aṣòfin díẹ̀ kan ti bẹ̀rẹ̀ ìgbésẹ̀ tàbí jíròrò lórí àwọn òfin àti ìlànà tí yóò máa de ètò ìdìbò ní pàápàá láti kojú àwọn ìpèníjà AI lásìkò ètò ìdìbò. Ní United Kingdom, bí àpẹẹrẹ, òfin tó wà nílẹ̀ lórí títàbù èèyàn ko rújú lórí dídá ààbò bo èèyàn lọ́wọ́ gbígbé ìròyìn irọ́ nípa ẹni náà àmọ́ òfin náà kò ya pọ́n-ọ́n-na tó bá di ọ̀rọ̀ àwòrán tàbí fídíò.[7]

Àwọn òfin àti ìlànà tí kò rújú ṣe pàtàkì láti ṣàrídájú ìwà gbangba làṣà ń ta àti láti ri pé wọ́n ń rí ìrànlọ́wọ́ tó yẹ lásìkò. Àwọn tó ń ṣe àgbékalẹ̀ ìlànà le pèsè àwọn ìlànà tó dúró ire láti ri pé ètò ìṣèjọba àwaarawa kò di àtẹ̀mẹ́rẹ̀, tí wọn yóò sì mú àdínkù bá àwọn ìpèníjà tí AI le ṣokùnfà rẹ̀.

## Ìgbésẹ̀ àkọ́kọ́
# Àwọn ìjọba nílò láti ṣe àtúnṣe òfin ètò ìdìbò

Àwọn ìjọba nílò láti ṣe àtúnṣe sáwọn òfin ètò ìdìbò láti ri dájú pé àwọn olóṣèlú, àwọn ẹgbẹ́ òṣèlú, àwọn iléeṣẹ́ ìmọ̀ ẹ̀rọ àtàwọn olùdìbò mọ̀ ní pàtó:

- bí wọ́n ṣe lè lo àwọn àwòrán, fídíò tàbí fọ́nrán tí wọ́n bá fi ìmọ̀ ẹ̀rọ gbé jáde fún àwọn ohun tó bá jọ mọ́ ètò ìdìbò;
- àwọn ohun èlò AI ni wọn kò le lò tàbí lò ní ìwọ̀ntúnwọ̀nsì fáwọn ohun èlò ìdìbò; àti
- bí wọ́n ṣe máa pín ẹ̀bi àti ìjìyà nígbà tí wọ́n bá tàpá sí òfin tó de ètò ìdìbò.

Láti ṣe àrídájú rẹ̀ pé wọn kò fòfin dé ìlànà ìbáraẹnisọ̀rọ̀ lórí ètò ìdìbò, àwọn òfin ètò ìdìbò tuntun gbọdọ̀ wà ní ìbámu pẹ̀lú àwọn ìpèníjà tí wọ́n ń dènà. Àwọn aláṣẹ tí kò gbára lé ẹnikẹ́ni tó ń mójútó AI lásìkò ètò ìdìbò máa nílò ìmọ̀ tó péye nípa ìmọ̀ ẹ̀rọ àti owó láti fi àwọn òfin náà múlẹ̀.

Ìlànà àti àgbékalẹ̀ òfin gbọdọ̀ sọ ìtumọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ tó ṣe kókó bí i àwọn dátà tí wọ́n fi ìmọ̀ ẹ̀rọ gbà, àwọn AI tí wọ́n fi ìmọ̀ ẹ̀rọ ṣe, àwọn ètò tó jẹ́ ti AI, àti àwọn ìròyìn tó lè ṣi èèyàn lọ́kàn àti láti lè mọ ìdí tí ìnílò fún àtúnṣe àwọn abala kan nínú òfin tó wà nílẹ̀ tẹ́lẹ̀. Ní àfikún, wọ́n gbọ́dọ̀ ṣàgbéyẹ̀wò láti ṣe àwọn òfin tó pọn dandan yìí:

- Kò gbọdọ̀ sí lílò, gbígbéjáde, fífihàn lójú àwòrán tàbí pín àwọn nǹkan tí wọ́n bá fi AI ṣe láti fi ní ipa lórí ètò ìdìbò. Bí àpẹẹrẹ, àwọn ìjọba nílò láti ṣe àgbéyẹ̀wò láti fòfin de lílo àwòrán, fídíò tàbí ohun tí wọ́n bá fi AI ṣe èyí tó ń ṣàfihàn àwọn olùdíje tàbí ìpolongo ìbò lọ́nà àìtọ́ tàbí tó lè ṣi èèyàn lọ́kàn tàbí tó lè tan ìròyìn òfégè nípa olùdíje tàbí ìpolongo ìbò, tàbí ètò ìdìbò náà gan.
- Àwọn olóṣèlú àtàwọn ẹgbẹ́ òṣèlú nílò láti máa ṣàmúlò ìwà gbangba làṣá ń ta nípa kíkọ sára àwọn àwòrán, ohùn, àti fídíò tí wọ́n bá lò, gbé jáde, ṣàfihàn tàbí tí wọ́n bá pín kiri lásìkò ìbò tí wọ́n bá fi AI ṣe pé AI ni àwọn fi ṣe é. Láti ṣe tàbí mú ìgbòòrò bá àwọn ààmì yìí, àwọn ìjọba nílò láti kẹ́kọ̀ọ́ lára àwọn ìwádìí ìmọ̀ sáyẹ́nsì àti látọ̀dọ̀ àwọn aráàlú. Àwọn aráàlú gbọdọ̀ lè tètè dá àwọn ààmì AI mọ̀ láì sí ìnira kankan pẹ̀lú fífi àwọn àwòrán, ọ̀rọ̀, àkókò, ipò àti àsìkò sọ́kàn.
- Àwọn ìjọba gbọdọ̀ fòfin dè é fáwọn ìkànnì orí ayélujára láti pọn ọ́n ní dandan fún àwọn tó ń ṣàmúlò ìkànnì wọn láti máa ṣàmì sáwọn fọ́nrán òṣèlú tí wọ́n bá fi AI ṣe àti láti gbé òfin tó fẹsẹ̀ múlẹ̀ kalẹ̀ lórí àwọn fọ́nrán tí wọ́n le máa gbé jáde lórí ìkànnì wọn láti dènà gbígbé àwọn ètò tí wọ́n fi AI ṣe tó lè da omi àláàfíà ìlú láàmú.

***Àwọn òfin ètò ìdìbò gbọdọ̀ lè dá sí chatbots, èyí tó lè pèsè àwọn ìròyìn tó lè ṣe èèyàn lọ́kàn nípa àwọn nǹkan tó ṣe kókó lórí ètò ìdìbò bíi ibi tí àwọn ibùdó ìdìbò wà, àwọn nǹkan ni èèyàn nílò láti dìbò, tàbí àwọn àkọ́ọ̀lẹ̀ ìwà ọ̀daràn nípa olùdíje.***[8]

## Ìpèníjà Kejì
# Àwọn ẹgbẹ́ òṣèlú kò ì tíì fẹnukò ohun tó ń jẹ́ pé ètò ìdìbò kò ní ẹja n bákàn nínú láyé AI yìí

Àwọn ẹgbẹ́ òṣèlú àtàwọn olùdíje lè ṣàmúlò àwọn ohun èlò AI láti fi pèsè àwọn ìròyìn òfégè, ṣe àgbéjáde àwọn fọ́nrán lọ́pọ̀ yanturu láti fi ṣi àwọn èèyàn lọ́kàn, gbígbé ìròyìn òfégè nípa èèyàn kan fáwọn olùdìibò tàbí yí àwọn  kókó ọ̀rọ̀ padà nípasẹ̀ ìṣàmúlò àwọn ìkànnì tí wọ́n fi ìmọ̀ ẹ̀rọ ṣe.

Láì sí ìlànà, àlàkalẹ̀ tó múná dóko tàbí ìlànà tí wọ́n yóò máa gbà ṣiṣẹ́, ewu wà pé àwọn ẹgbẹ́ òṣèlú lè máa lo AI lọ́nà tí kò ní jẹ́ káwọn olùdìbò ní ìgbàgbọ́ nínú ètò ìdìbò, pín ìròyìn òfégè kiri àti ní ipa tí kò tọ̀nà lórí àbájáde èsì ìdìbò.

Láì sí ìfẹnukò lórí ìlànà tàbí òfin kan gbòógì, àwọn ẹgbẹ́ òṣèlú yóò tún máa gbìyànjú láti tẹ̀síwájú lórí lílo AI lójúnà àti ri pé àwọn kò wà lẹ́yìn àwọn alátakò wọn.  Ọ̀rọ̀ òṣèlú le lágbára débi tó jẹ́ pé àwọn olóṣèlú yóò máa sáré lílo AI láti borí níbi ètò ìdìbò láì bìkítà lórí ipa tí ìgbésẹ̀ bẹ́ẹ̀ le ní lórí ṣíṣe ètò ìdìbò tó kẹ́ṣe jári.

## Ìgbésẹ̀ Kejì
## Àwọn ẹgbẹ́ òṣèlú ní láti ìlànà ìhùwàsí tí yóò máa ṣe atọ́nà láti gba ẹ̀bi tàbí ààre lórí ìwà òṣèlú tí wọ́n bá hù láyé AI yìí

Ìlànà ìhùwàsí jẹ́ ojúnà láti jẹ́ káwọn èèkàn nínú òṣèlú gbà láti ní ìfarajìn sí ṣíṣe ètò ìdìbò tí kò ní kọ́nú n kọ́họ nínú  nípa híhu àwọn ìwà kan tàbí kọ̀ láti hu àwọn ìwà mìíràn. Ìlànà ìhùwàsí lórí lílo AI ṣe àtìlẹyìn fún ìwà gbangba làṣá ń ta àti ṣíṣe òótọ́ lórí lílo ìmọ̀ ẹ̀rọ yìí fún ètò ìdìbò.

Irúfẹ́ àwọn ìlànà ìhùwàsí yìí ti wà láwọn ìlànà òfin kan. Bí àpẹẹrẹ, lọ́dún 2023, àwọn ẹgbẹ́ òṣèlú márùn-ún ní Swiss ni wọ́n jẹ́jẹ̀ẹ́ láti lo AI lọ́nà tó tọ̀nà àti pé àwọn kò ní lò ó láti fi tàbùkù tàbí bu ẹnu àtẹ́ lu ẹnikẹ́ni. Níbi ètò ìdìbò sí ilé aṣòfin ilẹ̀ Yúróòpù lọ́dún 2024, àwọn ẹgbẹ́ òṣèlú ilẹ̀ Yúróòpù fẹnukò lórí ìlànà ìhùwàsí kan lórí lílo AI lásìkò ètò ìdìbò náà. Àwọn orílẹ̀ èdè bí i U.K. àtàwọn mìì ti gbìyànjú láti gbé àwọn ìlànà bẹ́ẹ̀ kalẹ̀.

Àwọ ìlànà ìhùwàsí nípa ìṣàmúlò AI fún ètò òṣèlú gbọ́dọ̀ jẹ́ jẹ́ káwọn ẹgbẹ́ òṣèlú ṣe àwọn nǹkan wọ̀nyí:

- **láti má lo AI láti fi pèsè àwọn fọ́nrán tó lè ṣi aráàlú tàbí ṣi olùdìbò lọ́kàn;**
- **ṣe ààmì sáwọn fọ́nrán tí wọ́n bá fi AI ṣe lọ́nà tí yóò yé àwọn tó bá ri (tí a bá wo ìlànà ìṣòfin tí a ti ṣàwárí rè ṣáájú àti bí ìbéèrè yìí ṣe gbọ́dọ̀ yá sí);**
- **kò gbọ́dọ̀ ṣe pín àwọn fanrán tí wọ́n fi ìmọ̀ ẹ̀rọ ṣe tó lè ṣi èèyàn lọ́kàn, kí wọ́n sì máa pariwo irúfẹ́ ìwà bẹ́ẹ̀ síta;**
- **kí wọ́n máa ṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tó tọ́ àti ṣàlàyé ìlànà tó yẹ fáwọn òṣìṣẹ́, ọmọ ẹgbẹ́, àwọn olùpolongo, àti àwọn alátìlẹyìn wọn lórí lílo AI fún ìpolongo ìbò;**
- **yàgò fún pípèsè, lílò, tàbí pínpín àwọn fọ́nrán tó lè ṣi èèyàn lọ́kàn tó fi mọ́ ṣíṣí ayédèrú àkáǹtì, bots, tàbí chatbots, láti fi yí ọkàn àwọn olùdìbò ríborìbo;**
- **ṣàgbéjáde ipele àmójútó sí chatbots wọn tí yóò máa darí àwọn tó ń ṣàmúlò íntánẹ́ẹ̀tì sáwọn ìròyìn ojúlówó nípa ètò ìdìbò; àti**
- **farajìn sí ṣíṣe àmójútó, àyẹ̀wò, àti àtúngbéyẹ̀wò ìṣàmúlò AI àtàwọn ohun èlò tó níiṣe pẹ̀lú AI lẹ́yìn ètò ìdìbò.**

## Ìpèníjà kẹta
## Ọ̀pọ̀ àwọn àlàkalẹ̀ ìlànà òfin ni kò gbáradì fún àwọn ìpèníjà tó lè tara AI yọ lórí ètò ìdìbò wọn àtàwọn ẹ̀ka tó ń rí sí ètò ìṣèjọba àwaarawa

Àwọn ìjọba máa ń gbé ọgbọ́n àtinúdá kalẹ̀ àtàwọn ètò láti kojú àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ bíi àjálù àdáyébá, ìjà àwọn ará ìlú tàbí àjàkálẹ̀ àrùn. Ọ̀pọ̀ àwọn ìjọba ni kò ṣetán láti kojú àwọn ìpèníjà tí AI le mú bá ṣíṣe ètò ìdìbò tí kò ní ẹja-n-bákàn nínú àti àwọn ẹ̀ka tó ń rí sí ètò ìṣèjọba àwaarawa.

Kíkojú àwọn ìṣoro tí AI le mú bá àṣeyọrí ètò ìdìbò jẹ́ ìpèníjà olójú púpọ̀.

Ìkíní, àwọn ìjọba kìí sábà ní ìmọ̀ àti àwọn ohun èlò tó yẹ láti fi tọpinpin àwọn ìròyìn òfégè tí wọ́n fi AI ṣe, àwọn irọ́ pọ́ńbélé, àtàwọn ìpolongo mìíràn tí wọ́n fi ìmọ̀ ẹ̀rọ gbé jáde lórí àwọn ìlànà ètò ìṣèjọba àwaarawa. Àìsí ìbáṣepọ̀ láàárín àwọn alẹ́nulọ́rọ̀ bíi àwọn àjọ ìjọba, àwọn ìkànnì orí ayélujára, àwọn iléeṣẹ́ ìròyìn àtàwọn àjọ ajàfẹ́tọ̀ọ́ tí kìí ṣe ti ìjọba ń dá kún àìsí ìmọ̀ kíkún láti ṣàwárì àwọn ìròyìn òfégè. Nígbà tí wọ́n bá ṣàwárí àwọn fọ́nrán tó mú ìfura lọ́wọ́, kò sí ìlànà tó fojú hàn láti tẹ̀lé lórí pínpín ìròyìn àti ṣíṣe àkóso èsì.

Ìkejì, ọ̀pọ̀ àwọn òṣìṣẹ́ ètò ìdìbò ni kò ní ìmọ̀ nípa AI láti lè fi mọ ìyàtọ̀ láàárín àwọn tó jẹ́ ìdúnkokò sí ètò ìdìbò, tí èyí kìí jẹ́ kí wọ́n le gbé ìgbésẹ̀ kankan. Àìní ìmọ̀ kíkún yìí tàn dé gbogbo àwọn ẹ̀ka tó ń rí sí ètò ìṣèjọba àwaarawa. Bí àpẹẹrẹ, kìí sí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ kíkún lórí ìdúnkokò ìmọ̀ ẹ̀rọ lórí ètò ìdìbò fáwọn òṣìṣẹ́ tó ń kó ìbò jọ, àti àwọn awòye lórí ètò ìbò, tí wọ́n wà nídìí dídá ààbò bo ètò ìdìbò, tí wọ́n ń léwájú lórí àwọn tí yóò máa dá ààbò bo ètò ìdìbò. Èyí yóò jẹ́ kó nira fún wọn láti dáhùn ìbéèrè tó bá jẹ mọ́ àwọn fọ́nrán tí wọ́n fi AI ṣe.

Ìkẹta, àwọn àjọ ìjọba kìí sábà ní ìmọ̀ ẹ̀rọ, àwọn òṣìṣẹ́ àti ìkápá tí wọ́n nílò láti fi ṣàmójútó àti kojú àwọn ìdúnkokò tó lè tẹ̀yìn AI jáde bó ṣe yẹ. Láìsí àwọn wọ̀nyí, àwọn tó ń ṣe ìlànà yóò máa fèsì sáwọn ìṣẹ̀lẹ̀ bó bá ṣe ń wáyé dípò gbígbé ìlànà ọgbọ́n àtinúdá kalẹ̀ láti dènà àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ bẹ́ẹ̀.

## Ìgbésẹ̀ Kẹta
## Àwọn aláṣẹ ètò ìdìbò nílò láti pèsè ikọ̀ tí yóò máa dènà àti ṣàtúnṣe sáwọn ìpèníjà tó bá kojú ètò ìdìbò nípasẹ̀ AI

Àwọn aláṣẹ ètò ìdìbò nílò láti ní ikọ̀ tó máa dá dúró lábẹ́ ìṣàkóso wọn tí yóò máa mójútó àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ètò ìdìbò tó nííṣe pẹ̀lú AI. Gbogbo àwọn alẹ́nulọ́rọ̀ tó ní nǹkan ṣe pẹ̀lú ètò ìdìbò àti ìṣèjọba àwaarawa ló gbọ́dọ̀ ṣe àtìlẹyìn fún ikọ̀ náà. Ikọ̀ náà gbọ́dọ̀ ní ìbáṣepọ̀ tó dán pẹ̀lú àwọn ilé iṣẹ́ ìròyìn, àwọn ìkànnì ayélujára àti àwọn tó ṣe kókó ní ẹkùn wọn àti ní ilẹ̀ òkèrè. Bákan náà ni wọ́n gbọ́dọ̀ ní aṣojú láti ẹgbẹ́ òṣèlú kọ̀ọ̀kan láti ṣàrídájú rẹ̀ pé àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ pàjáwìrì tó bá ń ṣẹ́yọ àti ọ̀nà lát kojú wọn ni wọ́n ń ṣàmójútọ bó ṣe yẹ.

Ikọ̀ náà nílò láti máa ṣiṣẹ́ lásìkò àti lẹ́yìn ètò ìdìbò láti ri pé wọ́n ń ṣàmójútó tó yẹ fún ìṣèjọba àwaarawa lọ́wọ́ ìkọlù kankan. Yóò jẹ́ ojúṣe ikọ̀ náà láti ṣiṣẹ́ lórí àgbédìde èsì tó gbòòrò fáwọn ará ìlú lórí ìdúnkokò AI sí ètò ìdìbò.  Èròǹgbà lórí èsì AI lórí ètò ìdìbò yóò ṣàfihàn ní gedengbe ìlànà tí wọ́n yóò máa gbà ṣiṣẹ́, àwọn ojúṣe wọn, àti ìlànà ìbáraẹnisọ̀rọ̀ tí wọn yóò máa ṣàmúlò àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Gbogbo àwọn alẹ́nulọ́rọ̀ lẹ́ka ìròyìn àti ayélujára gbọ́dọ̀ kópa nínú ṣíṣe àmúṣe àwọn èròǹgbà yìí láti mú àdínkù bá ìtànkálẹ̀ ìkọlù àti láti tètè máa ta àwọn ará ìlú lólobó.

Àwọn aláṣẹ ètò ìdìbò láti pe ìpàdé àwọn alẹ́nulọ́rọ̀ láti jíròrò níbi tí àwọn tí ọ̀rọ̀ kàn yóò kẹ́kọ̀ọ́ nípa ìṣàmúlò AI, bí wọ́n ṣe le dán èsì rẹ̀ wò àti báwọn èèyàn ṣe lè gbà á mọ́ra sí, tó fi mọ́ ìpalára tó lè jẹ jáde èyí tí àwọn alẹ́nulọ́rọ̀ le ṣàmúlò.

The AI Electoral Response Plan nílò ṣàgbéyẹ̀wò ẹ̀tọ́ àwon aráàlú láti ri pé wọ́n dènà ìdúnkokò ìtọpinpin aráàlú àti ìwòye wọn lórí ọ̀rọ̀ òṣèlú.

***Láti ri dájú àwọn ìpèníjà tó ń kojú ètò ìdìbò látara AI jẹ́ kíkojú bó ṣe yẹ, ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tó jinà nípa AI àti ètò ààbò orí ayélujára gbọ́dọ̀ wà fáwọn tó ń ṣiṣẹ́ lórí ètò ìṣèjọba àwaarawa àti ètò ìdìbò, tó fi mọ́ àwọn tó ń ṣiṣẹ́ ní ibùdó ìdìbo àtàwọn olùwòye ètò ìdìbò.***

## Ìpèníjà Kẹrin
## Ipa AI lórí ètò ìdìbò máa ń ní àtìlẹyìn àwọn èèyàn tó ń lo ọ̀pọ̀ ìlànà

Bí ọ̀pọ̀ àwọn ìkọlù tí AI jẹ́ sí ètò ìdìbò jẹ́ nǹkan tó lè kan ọ̀pọ̀ orílẹ̀ èdè ṣàlàyé ìdí tó fi ṣòro fún àwọn aládàni láti dá kojú rẹ̀. Ìpèníjà àìsí ìmọ̀ àti àwọn ohun èlò tó ṣe déédéé láàárín àwọn ìjọba wà lára àwọn nǹkan tó ń dákún ìṣòro yìí, báwọn kan kò ṣe ní àwọn onímọ̀, ohun èlò àti ìkápá tí wọ́n nílò láti fi ṣàwárí àti kojú àwọn ìdúnkokò AI lórí ètò ìdìbò bó ṣe yẹ.

Láìsí ìlànà kan pàtó káàkiri àgbáyé, ó máa ṣòro láti lè fojú àwọn tó ń ṣiṣẹ́ náà winá òfin nítorí ìyàtọ̀ ìlànà òfin, ìkápa láti ṣe ìwádìí àti ibi tí ọwọ́ja òfin kálukú mọ.

Àwọn orílẹ̀ èdè tí ètò ìṣèjọba àwaarawa ti ń jẹ́ àmúlò nílò láti mọ̀ pé ìkọlù sí ìṣejọba àwaarawa kan jẹ́ ìkọlù sí ìlànà tó so àwọn ìṣèjọba àwaarawa yóòkù pọ̀. Àjọṣepọ̀ láti gbé ìgbésẹ̀ tó yẹ ṣe pàtàkì láti dá ààbò bo ìṣèjọba àwaarawa, lékún ìfọkàntán aráàlú àti ṣíṣe àrídájú pé ètò ìdìbò kò di ohun àtẹ̀mẹ́rẹ̀ káàkiri àgbáyé.

## Ìgbésẹ̀ Kẹrin
## Àwọn ìjọba nílò láti ṣe ìdásílẹ̀ àjọ tí yóò ṣàkóso ètò ìdìbò AI ní àgbáyé àti ìgbìmọ̀ àgbáyé lórí ìlànà fún ìfẹnukò nípa àtìlẹyìn òfin lórí àwọn nǹkan tó níiṣe pẹ̀lú AI lórí ètò ìdìbò

Àwọn orílẹ̀ èdè nílò láti ṣe ìdásílẹ̀ àjọ àgbàyé kan láti kẹ́kọ̀ọ́ lórí bí wọ́n ṣe máa ma dáhùn nígbà tí AI bá ti ń nípa lórí ètò ìdìbò:  the International AI Electoral Trustkeepers.

Èyí yóò jẹ́ àkójọ àwọn onímọ̀ àtàwọn iléeṣẹ́ tí wọ́n ní ìfarajìn láti ṣàwárí, kíkojú àti mímú àdínkù bá ipa AI lórí ètò ìdìbò. Wọ́n máa ṣiṣẹ́ gẹ́gẹ́ olùpèsè ohun èlò ìmọ̀ ẹ̀rọ fáwọn orílẹ̀ èdè tí AI le nípa lórí ètò

ìdìbò wọn. Wọ́n máa pèsè àwọn onímọ̀, ohun èlò, àti ìfọwọ́sowọ́pọ̀ láti kojú àwọn ìdúnkokò sí ètò ìdìbò àgbáyé. Ìgbìmọ̀ “International AI Electoral Trustkeepers” yóò pèsè àtìlẹyìn lásìkò ìṣòro nípa pípèsè ìgbìmọ̀ ayára-bí-àṣá láti ṣe ìrànwọ́ lásìkò ìbò àti láti ṣàkóso, gbé ọgbọ́n àtinúdá kalẹ̀ láti kojú àwọn ìṣòro láwọn ibi tó ti ga.

Ìdásílẹ̀ ìgbìmọ̀ “International AI Electoral Trustkeepers” le wáyé látara tàbí àkójọ àwọn ìgbìmọ̀ tó ti wà nílẹ̀ tẹ́lẹ̀ pẹ̀lú èròǹgbà láti ṣe ìrànwọ́ ètò ìdìbò tàbí láti da ààbò bo àwọn orílẹ̀ èdè tó ṣeéṣe kí wọ́n wà nínú ewu AI. Bí àpẹẹrẹ, Wọ́n le gbé àwọn ìgbésẹ̀ láti pèsè àwọn ohun èlò AI tuntun tàbí mú ìgbòòrò bá àwọn tó ti wà tẹ́lẹ̀ (gba àwọn onímọ̀ fún ìgbà díẹ̀ tàbí gba àwọn akọ́ṣẹ́mọṣẹ́) sí àwọn ẹ̀ka tó ń ṣe àtìlẹyìn fún ètò ìdìbò ní àjọ ìṣọ̀kan àgbáyé,[9] èyí tó máa ń ṣe ìrànwọ́ fáwọn orílẹ̀ èdè tó jẹ́ ọmọ ẹgbẹ́ rẹ̀ láti ṣètò ìdìbò tó ṣàfihàn ohun tí àwọn ará ìlú ń fẹ́, tí gbogbo àwọn alẹ́nulọ́rọ̀ yóò gbóríyìn fún. Àjọ nascent International Network of AI Safety Institutes le lò ìgbésẹ̀ láti ṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ fáwọn ìgbìmọ̀ Electoral Trustkeepers kí wọ́n sì lò wọ́n káàkiri àgbáyé lórí àwọn iṣẹ́ pàtàkì.

Nígbà tí wọ́n bá nílò ìmọ̀ àwọn akọ́ṣẹ́mọṣẹ́, àwọn ẹ̀ka aládàni bíi AI àtàwọn ilé iṣẹ́ tó wà lẹ́yìn ìmọ̀ ẹ̀rọ Tsch Accord le ṣe àtìlẹyìn International AI Electoral Trustkeepers láti kojú ìdásí AI lórí ètò ìdìbò.[10]

Gbígbé ara lé àtìlẹyìn òfin náà yóò ṣe pàtàkì láti ṣe ìwádìí àti gbé ìgbésẹ̀ òfin tó yẹ lórí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí wọ́n bá ti lo AI láti dá sí ètò ìdìbò, tí èyí yóò sì mú kí ìfọwọ́sowọ́pọ̀ wà láàárín àwọn akópa káàkiri gbogbo ẹ̀ka, ṣe ìrànwọ́ láti ṣàwárí àti pín àwọn ẹ̀rí tó bá ń jáde ní ọ̀pọ̀ orílẹ̀ èdè, àti láti ri pé àwọn tó ń lo AI láti fi dojú ètò ìdìbò délẹ̀ kò lo òfin orílẹ̀ èdè kan láti fi móríbọ́ lọ́wọ́ kíkojú ìgbéjọ́.

Irúfẹ́ ìlànà yìí ni wọ́n ti ṣàmúlò láti kojú àwọn ìpèníjà tó níiṣe pẹ̀lú ọ̀pọ̀ orílẹ̀ èdè bíi ìgbógunti ìwà ọ̀daràn orí ayélujára, lílu jìbìtì lórí ayélujára, ìgbéṣùmọ̀mí, títẹ ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn lójú mọ́lẹ̀, àti ogun nípasẹ̀ àtìlẹyìn àjọṣepọ̀ orílẹ̀ èdè àti pínpín àwọn ẹ̀rí.

***Àwọn ètò àti ìlànà àgbáyé yìí nílò láti wáyé ní gbangba láti ṣàrídájú ààbò àwọn ẹ̀tọ́ tó yẹ.***

## Ìkádìí

Ipa AI lórí ìṣèjọba àwaarawa jẹ́ ohun tí kò ṣe é yípadà.

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé iṣẹ́ dojúkọ àwọn ewu tí AI le fà, ó ṣeéṣe láti fi AI mú ìgbòòrò bá ètò ìṣèjọba àwaarawa. Àwọn òṣìṣẹ́ ètò ìdìbò le lo AI láti fi ṣe àwọn iṣẹ́ tó bá le ní àṣeyọrí. Àwọn ohun èlò yìí le mú kí ìdìbò rọrùn si, kó sì jẹ́ kí àwọn èèyàn túnbọ̀ kópa lásìkò ìdìbò. Bí àpẹẹrẹ, lásìkò ètò ìdìbò Pakistan lọ́dún 2024, adarí ẹgbẹ́ òṣèlú alátakò kan tó wà ní ọgbà ẹ̀wọ̀n ṣàmúlò ìmọ̀ ẹ̀rọ láti fi bá àwọn olùdìbò sọ̀rọ̀ láti àhámọ́ tó wà.[11] Láti tẹ̀síwájú, àwọn tó ń jà fún ètò ìṣèjọba àwaarawa ní láti ṣàwárí ọ̀nà tí AI fi le mú ètò ìṣèjọba àwaaraw rọrùn si.

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé dídá ààbò bo ìṣèjọba àwaarawa lọ́wọ́ ìdúnkokò àwọn tó ń lo AI lọ́nà àìtọ́ nílé àti nílẹ̀ òkèrè ni pàtàkì báyìí, èyí gba ìgbésẹ̀ ní ìpele méjì;

Láàárín orílẹ̀ èdè, àwọn ìjọba gbọdọ̀ ṣe àtúnṣe àwọn òfin wọn, àwọn ẹgbẹ́ òṣèlú gbọdọ̀ ṣiṣẹ́ papọ̀, táwọn aláṣẹ ètò ìdìbò náà sì gbọdọ̀ gbáradì láti dá ààbò bo ìṣèjọba àwaarawa lọ́wọ́ àwọn tí wọ́n máa ṣàmúlò AI lọ́nà àìtọ́.

Láàárín orílẹ̀ èdè kan sí òmíràn, ìfọwọ́sowọ́pọ̀ ṣe pàtàkì. Kò sí orílẹ̀ èdè tó le dá kojú ìpèníjà AI. Àwọn orílẹ̀ èdè nílò láti jẹ́ kí òfin wọn wà ní ìbámu láti kojú ìpèníjà AI lórí ètò ìdìbò. Èyí yóò mú àlékún bá bí orílẹ̀ èdè ṣe lè dá ààbò bo ara rẹ̀ ní òhun nìkan àti láti jọ ṣiṣẹ́ papọ̀ pẹ̀lú àwọn orílẹ̀ èdè mìíràn láti dènà àwọn tó bá fẹ́ dojú ètò ìṣèjọba àwaarawa délẹ̀ káàkiri àgbáyé.

Bí a bá bẹ̀rẹ̀ àwọn ìgbésẹ̀ yìí lónìí, a máa ṣàgbédìde ètò ìṣèjọba àwaarawa tó dúró ire, tó fàyè gba tẹrú tọmọ àti èyí tó ṣe é fọkàn tán lẹ́yìnwá ọla.

## Notes


1. Èdè Gẹ̀ẹ́sì ni wọ́n fi ṣe àkọ́ọ́lẹ̀ iṣẹ́ yìí tí wọ́n pé àkọ́lé rẹ̀ ní “AI in the Ballot Box.” Faoziyah Saanu-Olomoda, ti iléeṣẹ́ ìròyìn BBC News Yoruba ló tu sí èdè Yorùbá.
2. Farrugia, B. (26 Oṣù Kọkànlá, 2024). Brazil’s electoral deepfake law tested as AI-generated content targeted local elections. DFRLab. https://dfrlab.org/2024/11/26/brazil-election-ai-deepfakes
3. For more information on how AI presents serious concerns for the safety of women, see: United Nations Educational, Scientific and Cultural Organization. (2023). Technology-facilitated gender-based violence in an era of generative AI (World Trends in Freedom of Expression and Media Development Series). https://unesdoc.unesco.org/ark:/48223/pf0000387483
4. Harward, C. (6 Oṣù Kejìlá, 2024). Likely Kremlin-backed election interference against Romania threatens Bucharest’s continued support for Ukraine and NATO. Institute for the Study of War. https://understandingwar.org/backgrounder/likely-kremlin-backed-election-interference-against-romania-threatens-bucharests
5. RFI. (23 Oṣù Kẹjọ, 2023). Élections au Gabon: polémique après des enregistrements supposés de candidats de l’opposition. RFI. https://www.rfi.fr/fr/afrique/20230823-%C3%A9lections-au-gabon-pol%C3%A9mique-apr%C3%A8s-des-enregistrements-suppos%C3%A9s-de-candidats-de-l-opposition
6. Palta, R., Angwin, J., & Nelson, A. (27 Oṣù Kejì, 2024). How we tested leading AI models performance on election queries. Proof. https://www.proofnews.org/how-we-tested-leading-ai-models-performance-on-election-queries; Impelli, M. (31 Oṣù Kẹwàá, 2024). Voting rights groups warn about AI generating unfounded claims in Spanish. Newsweek. https://www.newsweek.com/2024-election-spanish-latino-voters-artifical-intelligence-concerns-1978170; Ott, H., & Lyons, E. (25 Oṣù Kẹfà, 2024). ChatGPT gave incorrect answers to questions about how to vote in battleground states. CBS News. https://www.cbsnews.com/news/chatgpt-chatbot-ai-incorrect-answers-questions-how-to-vote-battleground-states
7. Stockwell, S., Hughes, M., Swatton, P., & Bishop, K. (2024). AI-enabled influence operations: the threat to the UK general election. CETaS Briefing Papers. https://cetas.turing.ac.uk/sites/default/files/2024-05/cetas_briefing_paper_-_ai-enabled_influence_operations_-_the_threat_to_the_uk_general_election.pdf
8. Kaye, R. (5 Oṣù Kẹrin, 2023). Australian mayor readies world’s first defamation lawsuit over ChatGPT content. Reuters. https://www.reuters.com/technology/australian-mayor-readies-worlds-first-defamation-lawsuit-over-chatgpt-content-2023-04-05
9. United Nations Department of Political and Peacebuilding Affairs. (2023). 2023 factsheet: electoral assistance. https://dppa.un.org/sites/default/files/electoral_assistance.pdf
10. AI Elections Accord (16 Oṣù Kejì, 2024). A tech accord to combat deceptive use of AI in 2024 elections. https://www.aielectionsaccord.com/uploads/2024/02/A-Tech-Accord-to-Combat-Deceptive-Use-of-AI-in-2024-Elections.FINAL_.pdf
11. Zhuang, Y. (11 Oṣù Kejì, 2024). Imran Khan’s ‘Victory Speech’ from jail shows A.I.’s peril and promise. The New York Times. https://www.nytimes.com/2024/02/11/world/asia/imran-khan-artificial-intelligence-pakistan.html

## Ètò ìmúlò lórí AI lágbàáyé ní ṣókí

**Ètò ìmúlò lórí AI lágbàáyé jẹ́ àjọṣepọ̀ iṣẹ́ IVADO, ìpìlẹ̀ṣẹ̀ ìwádìí àti ìmọ̀ ti Canada ní ilé ẹ̀kọ́ Université de Montréal, àti AI + Society Initiative ní ilé ẹ̀kọ́ gíga fásitì, University of Ottawa, pẹ̀lú èròńgbà láti pèsè àwọn ìlànà àti ètò tó ṣe é múlò fáwọn tó ń ṣètò káàkiri àgbáyé lórí àwọn ọ̀nà tí wọ́n lè gbà láti kojú ìpèníjà AI tó ń bá gbogbo ayé fínra.**

fún iṣẹ́ àkọ́kọ́ yìí, àwọn ọ̀jọ̀gbọ́n Catherine Régis àti Florian Martin-Bariteau kó àwọn onímọ̀ nípa AI káàkiri àgbáyé jọ láti ṣe àgbékalẹ̀ àwọn ìlànà àti ètò ìdánilẹ́kọ̀ọ́ lójúnà àti dá ààbò bo ipa AI lórí ètò ìṣèjọba àwaarawa àti ètò ìdìbò. Àlàyé yìí jẹ́ ṣíṣe lẹ́yìn ìpàdé ọ̀sẹ̀ kan tí Società Italiana per l'Organizzazione Internazionale (SIOI) ṣe agbátẹrù rẹ̀ ní Rome, Italy, nínú oṣù Kejìlá, ọdún 2024. Ó jẹ́ kíkọ pẹ̀lú àtìlẹyìn Réjean Roy, adarí ẹ̀ka Knowledge Mobilization, IVADO.

*Àkànṣe iṣẹ́ yìí jẹ́ ṣíṣe, ọpẹ́ pàtàkì sí ìdásí Fonds de recherche du Québec, CEIMIA, alága Canada CIFAR lẹ́ka AI and Human Rights ní Mila àti alága ẹ̀ka ìwádìí nípa ìmọ̀ ẹ̀rọ àti àwùjọ ní ilé ẹ̀kọ́ gíga University of Ottawa, àti ìrànlọ́wọ́ ikọ̀ Délégation du Québec à Rome àti SIOI fún ṣíṣe àgbákalẹ̀ ìpàdé náà.*

*Àwọn ìwòye tó wà nínú àkọ́ọ́lẹ̀ yìí jẹ́ ti àwọn òǹkọ̀wé kọ wọ́n nìkan.*



**Catherine Régis** jẹ́ ọ̀jọ̀gbọ́n lẹ́ka ìmọ̀ òfin ní ilé ẹ̀kọ́ gíga fásitì Université de Montréal àti adarí Social Innovation and International Policy, IVADO. Gẹ́gẹ́ bí onímọ̀ nípa ìṣèjọba AI, ó wà lára àwọn tó ń darí ìwádìí ètò ní ilé ẹ̀kọ́ Canadian AI Safety Institute, tó sì tún jẹ́ alága Canada CIFAR ní AI àti ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn, Mila.



**Florian Martin-Bariteau** ni alága ẹ̀ka ìwádìí nípa ìmọ̀ ẹ̀rọ àti àwùjọ àti adile ọ̀jọ̀gbọ́n lẹ́ka ìmọ̀ òfin ní ilé ẹ̀kọ́ gíga fásitì University of Ottawa níbi tó ti ń darí ètò AI pẹ̀lú àwùjọ àti Centre for Law, Technology and Society. Ó jẹ́ alájọṣe ẹ̀ka ìmọ̀ Berkman- KleinCentre ní ilé ẹ̀kọ́ Havard University.



Olùrànlọ́wọ́ ọ̀jọ̀gbọ́n ní Lincoln Alexander School of Law ní ilé ẹ̀kọ́ Toronto Metropolitan University, **Jake Okechukwu Effoduh** ń ṣiṣẹ́ lórí òfin AI àti ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn ní àgbáyé. Ó dá sí ìdàgbàsókè ṣíṣe iṣẹ́ lórí àwọn ìlànà AI lọ́pọ̀ orílẹ̀ èdè, tó sì léwájú ọ̀pọ̀ ìwádìí àkànṣe iṣẹ́ lórí Canada-Africa.



**Juan David Gutiérrez**, adile ọ̀jọ̀gbọ́n ní ilé ẹ̀kọ́ gíga fásitì University of Andes, Bogóta, kẹ́kọ̀ọ́ nípa àjọṣepọ̀ tó wà láàárín ètò ìjọba àti àwọn ìmọ̀ ẹ̀rọ. Gẹ́gẹ́ bí onímọ̀ ọmọ ẹgbẹ́ Global Partnership on Artificial Intelligence (GPAI), ó wà lára àwọn tó darí àkànṣe iṣẹ́ gbígbé àwọn àbọ̀ ìwádìí iye sí ojútáyé.



**Gina Neff** jẹ́ ọ̀jọ̀gbọ́n ìlo AI ní Queen Mary University of London, tó sì ń darí Minderoo Centre for Technology and Democracy ní ilé ẹ̀kọ́ University of Cambridge. Àwọn ìwádìí rẹ̀ ṣàfihàn ipa tí ìmọ̀ ẹ̀rọ ń kó lórí iṣẹ́ àti ìgbé ayé ojúmọ́ ọmọnìyàn.



Onímọ̀ nípa òfin tó ń ṣiṣẹ́ lórí òfin ìgbàlódé, **Carlos Affonso Pereire de Souza** ń darí ẹ̀ka ìmọ̀ ẹ̀ró àti àwùjọ ní Rio de Janeiro. Gẹ́gẹ́ bí ọ̀jọ̀gbọ́n nínú ìmọ̀ òfin àti ìmọ̀ ẹ̀rọ, ó ti kópa ló lòòrìn sí ìpèsè òfin ààbò àkọ́ọ́lẹ̀ ara ẹni lórí ayélujára ní orílẹ̀ èdè Brazil.



Ọ̀jọ̀gbọ́n nípa òfin aládàni ní Université Paris 1 Panthéon- Sorbonne, **Célia Zolynski** jẹ́ onímọ̀ nípa òfin ìgbàlódé àti ọgbọ́n ẹni. Gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára àwọn adarí ìwòye AI ìyẹn AI Observatory ní Paris 1, ó fojúsun fífí òfin de AI àti ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn.

Àjọṣepọ̀ iṣẹ́ látọwọ́ àwọn

Pẹ̀lú àtìlẹyìn

Àkànṣe iṣẹ́ yìí jẹ́ ṣíṣe látàrí ìpèsè owó látọwọ́ àjọ Canada First Research Excellence Fund.